**Lakaye Ọrọ**

ENITI o ba gba mi gbọ o gba Baba mi ti mbe l'orun gbọ. E o si mo otitọ, otitọ yio si sọ nyin di ominira.

# Irohin Yoruba

No. 819 FEBRUARY 15 — FEBRUARY 21, 1961 KOBO MEJI (2D)


Dara fun Ẹjẹ ...de, Ọmọ... Agba ati Aboyun
O wa fun tita kakiri ile-egbogi

# OYE AGURA DI AKATA-KITI BABA ATI ỌMỌ NDU OYE NA

## Awọn Afọbajẹ ko i fi ohun ṣọkan

GBAGURA, Abẹokuta.

LATI igba ti Alaiyeluwa Ọba Ṣobẹkun Keji, Agura Gbagura, ti w'aja (gẹgẹbi a ti rohin si oju ewe kinni Iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ kẹsan oṣu kọkanla ọdun to kọja yi) ni rogbodiyan ti wa nilẹ larin awọn ọmọ-oye ti o tọ lati jẹ oye ropo rẹ. Ọrọ na si di akitiyan larin ogunlogọ awọn ọmọ oye ti o njijadu pe ki oye na bọ si ọwọ awọn.

Ninu awọn ọmọ oye na ni:- Raufu Adeọṣun, Rasaki Aderinale, ati Ọmọ-Ọba S. A. Johnson, ti o nṣiṣẹ ni ile iṣẹ 'Leventis l'Eko. Ninu awọn ọmọ-oye na baba ati ọmọ, ẹgbọn ati aburo wa ninu awọn ti o tun wa ndu oye na lati jẹ.

Nigbati akitiyan na bẹrẹ, Minista Alamojuto Ẹto Ifinijoye Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun kowe si gbogbo idile oye Ọba Agura ni Gbagura, Abẹokuta, pe ki nwọn ṣe ipinnu lori ọmọ-oye kan pataki ti oye na ba kan lati jẹ ropo ọba ti o w'aja.

Lati igbana ni rogbodiyan na ti tubọ nga si i, ti awọn ọmọ-oye si tubọ npọ si i, to bẹ ẹ ti nwọn ko ti i le fi ẹnikan ṣe olori lati jẹ oye na . Awọn Afọbajẹ paapa ko i ti f'ohun ṣọkan lori ẹnikan pataki. Ṣugbọn ti ọmọ-oye ti o farahan julọ niti Ọgbẹni Raufu Adeọṣun. On na ni ọrọ rẹ si wa lori ero larin awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, awọn idile Ọba Agura ati awọn Afọbajẹ nisisiyi.

Gẹgẹbi alaye ti Adele Ọba Agura ati Olori awọn Afọbajẹ, Oloye Y. O. Lalekan Osi Iddo, ṣe fun akọwe irohin wa nipe, "nigbati awọn afọbajẹ ba ṣe eto tan, gbogbo enia ni yio ma a gbọ nipa ẹniti nwọn ba yan ni Agura titun."



Oloye Y. O. Lalekan, Osi Iddo, Olori awọn Afọbajẹ



...ASAKI ADERINALE



ỌMỌ-ỌBA S. A. JOHNSON

## Ọkẹ mẹwa Afọju lo wa l'Oke Ọya

KADUNA.

AWỌN alakoso ẹgbẹ ti nṣe itọju awọn afọju ni Ipinlẹ Ariwa ṣe ikede laipẹ yi pe iye awọn afọju to wa ni Ipinlẹ na jẹ ọkẹ mẹwa (200,000).

Ninu ikede na awọn alakoso ẹgbẹ yi sọ pe awọn nfẹ owo lati le ma a fi kọ awọn afọju na ni ẹkọ iṣẹ ọwọ, eyiti yio ṣe wọn ni anfani. Nwọn tun sọ pe iye ti ẹgbẹ na ni lọwọ nisisiyi ko to lati fi tọju ogunlogọ awọn afọju Ipinlẹ Ariwa ati wipe owo ni ẹgbẹ na si nfẹ lati le jẹki eto ẹkọ awọn afọju na ma a lọ daradara.

Nwọn ni iranlọwọ awọn ara ilu ko ti i to bi ẹgbẹ na ti nfẹ.

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

# Igbimọ Musulumi ṣe ipinnu ọjọ awẹ

IPETU IJẸSHA.

NI ibi ipade Igbimọ Apapọ Musulumi Naijiria (United Muslim Council of Nigeria) ti nwọn ṣe lọdunni ni Gbọngan Apesi ilu Ipetu-Ijẹsha, ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ati ni ọjọ keji rẹ, ni nwọn panupọ ṣe ipinnu pe ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni nwọn yio kirun aṣamu, nwọn yio si bẹrẹsi gba Awẹ ni ọjọ keji rẹ.

Lẹhin ti nwọn ti yin Alhadji S A. T. Awẹlẹnjẹ fun iṣẹ iwuri ti o ti nṣe fun Igbimọ na ati fun ijọ Musulumi, nwọn wa fi ohun ṣọkan yan Alhaji na ni Olori wọn titi lailai. O si dupẹ lọwọ wọn, o ni ko ni ero pe, nwọn le da on ni ọla na.



Alhaji S. A. T. Awẹlẹnjẹ

Igbimọ na ṣe atako iwa ti awọn rọbirọbi Alhadji nhu. Nwọn ni nwọn ko lọ jọsin fun Ọlọrun ni Mẹka ati Mẹdina. Nwọn si nlọ ra Fila Hadji ,(Sabaka) ni Kano ati Mọṣalaṣi Jimọ, nwọn si nde e kakiri, nwọn npe ara wọn ni Alhadji.

Igbimọ na ni aṣa buburu ni eyi, nwọn ṣe ipinnu lati wa iranwọ Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ati ti awọn Ijọba Ipinlẹ Naijiria lati fi opin si aṣa na. Nwọn si ni nwọn yio tun ṣe ipade ni ọdun tombọ pẹlu Ogo Oluwa.O le ni ẹgbẹdogun (3,00) enia to wa si ibi ipade na.

## Abẹkẹ fi pọnun mẹwa tan ọran

MUSHIN.

ADAJỌ Kotu Ibilẹ ni Mushin, Ọgbẹni Jaiyeọla ni ki ọdọmọbinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Sidikatu Abẹkẹ lọ fi pọnun mẹwa (£10) tanran tabi ki o lọ ṣe ẹwọn oṣù kan onišẹ-aṣekara nitori pe o jẹbi ẹsun ti awọn Ọlọpa fi sun pe o ja ija-ajangbila ni ile ita onjẹ (hotel) kan ni Mushin, ija na si pọ to bẹẹgẹẹ ti on pẹlu ẹniti nwọn nja fọ awọn ohun elo ile ita onjẹ na.

Adajọ na tun palaṣẹ pe lẹhin ti Sidikatu ba ti tan ọran na ki awọn Ọlọpa wa a lọ si Ibadan ni ọdọ awọn obi rẹ.

Ninu ọrọ rẹ ki o to ṣe idajọ, Adajọ na ba Sidikatu sọrọ pupọ. O sọ fun un pe ọti mimu ko dara fun ojugba rẹ, ati pe ti ko ba fi iru iwakiwa ti o nhu silẹ, apẹlẹwọn ni yio jẹ. O si tun gba a ni imọran pe ki o lọ wa ọkọ pataki fẹ ki o si joko ti i, nitori igbẹhin ni pataki. Adajọ ni nipa bayi ni o le fi tun igbesi aiye rẹ ṣe.

## Awọn ọmọ Akinlade sinku rẹ

ỌKAKA-ỌYỌ.

AGBỌ so'gbanu ni irohin iku Ọgbẹni Joseph Akinlade to ngbe Ode Akere, Ibadan. Ọgbẹni Akinlade ku si ile rẹ ni Ọkaka-Ọyọ.

Ki ilẹ ọjọ keji ti o ti jalaisi to mọ, ni deede agogo meje alẹ ni awọn Ijọ Onitẹbọmi ti pe si ibi oku na, nwọn si gbe e lọ si ori itẹ..

Awọn ọmọ oku na, paapa akọbi rẹ, Ọgbẹni Joshua Ogundipẹ ti o ngbe Yonso-Jamasi (Ghana) n'awo-n'ara ni ibi aṣeyẹ isinku na, nwọn si nawo bakanna nigbati nwọn ṣe isin ijade oku na ni Ṣọọṣi Onitẹbọmi laipẹ yi.


## IṢAKA, AWỌ-ARA TI KO LẸWA FẸRẸ BA AYỌ-ỌMỌGE RẸ JẸ



1. Pẹlu gbogbo orin-ijo ti o ndun-yungba Susie ko ri ẹni aunmo o ba a jo, inu rẹ si bajẹ, ti o ba se pe Joseph ti pe e pe ki o wa ba on jo ni!

2. Nigbati Prudence ọrẹ Susie ri i ti o nsunkun, o mọ iru ibanujẹ ti o wa fun un. On paapa i ni arun oburẹwa iṣaka ara ri. O sọ aṣiri rẹ fun Susie . . . .



3. Susie tẹle imọran rẹ, o lọ s'oja o bere fun MentholatuM. Lẹhin ọjọ mẹta o ri Prudence, o wipe 'wo oi awọ-ara mi ti jọlọ o si ndan nisisiyi"

4. Ngbati nwọn tun ni ere... ijo gbogbo enia ni o ngbe Susie jo 'opelopẹ MentholatuM' ni e... ro nigbati Joseph di ẹniti ... mba a jo ti o si ngbadun rẹ.

Ooju, iṣaka tabi awọ ti o hunjẹ nfẹ MentholatuM. Ṣa fi pa ara... o ngmu u jọlọ, o ngmu u dan o si nṣe iwosan, o ngmu awọ-ara jọlọ ati kunna, o ngmu awọ-ara jọlọ ki o kunna ki o si rẹwa.
Ri i daju pe Men-tho-lay-tum gan an ni o ra ti o wa ninu agolo ati idẹ gẹgẹbi iru iwonyi. Maṣe ra awọn adamọdi o.
Awọn kanṣoṣo ti o nṣe e na nig...



MENTHOLATUM CO. LTD
(Est. 1889), Slough, England

MENTHOLATUM

IPARA TI O DARA JU.


## Susanah lugbade awọn onijibiti, o fi owo ọbẹ ta tẹtẹ

IGBOBI.

LẸNULỌLỌYI ni rogbodiyan kan ṣẹlẹ ni opopo Igbobi nigbati iyawo'le kan ti orukọ rẹ njẹ Susanah lọ lugbadi awọn onitẹtẹ ti nwọn npe ẹgbẹ wọn ni "Eyi-jẹ Eyi-o-jẹ." Bi Susanah ti nlọ si ita ọbẹ ni owurọ ọjọ na ni o ba ri awon ti nta tẹtẹ yi loju ọna.

O duro ti wọn, o si ngbọ nkan ti wọn nwi, o si tun nri gẹgẹbi nwọn ti ṣe nta tẹtẹ na ati bi nwọn ti ṣe nje owo mọ ara wọn lọwọ. Oju rẹ wọ tẹtẹ na, ni o ba tu ibiti o fi owo si, lo ba bẹrẹsi ba wọn ta.

Boya on yio jẹ ni o ti ṣe fi pọnun mẹrin (£4) owo ti ọkọ rẹ ko fun un pe ki nwọn fi jẹun di ipari oṣu ta tẹtẹ tan. Nigbati o na gbogbo owo na tan ni oju rẹ to mọlẹ. O duro fun bi iṣẹju diẹ, kò si mọ eyi ti on yio ṣe.

Nigbati o ṣe, o wa bẹrẹsi bẹ awọn ata-tẹtẹ yi pe ki nwọn dakun, bi o tilẹ jẹ diẹ ninu owo na ki nwọn jọwọ fun on nitoripe owo onjẹ ti ọkọ on fun on ni, pe ki awọn o fi jeun di ipari oṣu na. Nwọn ko tilẹ da lohun, nṣe ni awọn arabi na nta tẹtẹ wọn lọ.

Nigbati Susanah ri pe nwọn ko kọ ibi ara si on, nṣe ni nwọn nta tẹtẹ wọn lọ, lo ba so mọ ọga wọn lẹwu, lo ba bẹrẹsi sunkun, lo nkigbe, lo nlọbosi ọlọpa. Bi ọgan ni olori awọn atatẹtẹ na ti ja ọwọ Susanah kuro lara rẹ ti on ati gbogbo ẹlẹgbẹ rẹ si tuka mọ Susanah lori.

# Itan ilu Aigbọdọjiyan

(Lati ọwọ S. B. Oluṣẹgun, Ẹffọn-Alaye, Ilesha)

INU mi dun wipe Olotu Iwe "Irohin Yoruba" ṣonda fun mi lati sọ itan arikọgbọn kekere yi fun gbogbo awọn onkawe "Irohin Yoruba" lati fi ṣe ẹkọ kọ ki nwọn si mọ wipe ko si ohunkohun ti o ṣoro fun ẹnikẹni ti o ba nronu jinlẹ lati ṣe. Lati inu ironu arojinlẹ ni imọ-ijinlẹ si ti nwa. Itan na lọ bayi :-

Ni aiye atijọ, ilu kan wa ni ọna jinjinrere, orukọ rẹ njẹ AIGBỌDỌJIYAN tabi ẸRIJIYAN. Itumọ eyi ni pe ẹnikẹni ko gbọdọ jiyan lori ohunkohun ti nwọn ba ba a sọ, iba a ṣe ara ilu na tabi alejo ti o ba wọ sinu ilu na. Ẹnikẹni ti o ba si ru ofin yi, oriṣa kan ti o wa ni oke-odo ilu na ni nwọn yio pa arufin na bọ.

AJAPA ṢE IPINNU

Nigbati o pẹ ti nwọn ti nlo ofin buruku yi ni ilu na, "Ajapa Tiroko, ọkọ yanrinbo; o kọle-kọle f'iran ba a jẹ, ẹlẹṣẹ-osun-baba-ọyẹ" gbọ okiki ilu yi, o si ṣe ipinnu lati lọ bẹ ilu na wo, ki o si tun pada wa si ile rẹ ni alafia.

Nigbati awọn enia Ajapa gbọ imọran ti o da yi, nwọn kilọ fun un pe ki o maṣe lọ rara, nitoripe gbogbo awọn enia ti o ti lọ si ilu na ko pada wa si ile wọn mọ, pipa ni Abọrẹ oriṣa ilu na pa gbogbo wọn bọ Oriṣa na, nitoripe nwọn kọlu ofin aigbọdọjiyan.

Ṣugbọn Ajapa jẹ ọlọgbọn pupọ. O kọkọ ro ni ọkan rẹ wipe, "Iwe logun, ero l'ọtẹ, bi a o ti ṣe e si ni o nṣikẹta rẹ," bi on ko ba ronu jinlẹ, on ko le mọ ọna ti on yio gba lati fi pin awọn ara ilu na lọwọ ofin-kofin ati iwa apania ti nwọn gbe kalẹ larin ilu wọn na. Nitori idi eyi, Ajapa lọ kọ ile kekere kan si eti ipado ti o dake rọrọ kan nitosi ilu rẹ, o joko sibẹ ni on nikan, o bẹrẹsi ro oriṣiriṣi ọna ti o le gba fi ṣẹgun ofin buruku na.

OFIN KINI

Lẹhin ọsẹ kẹta ti Ajapa ti wa ni eti ipado yi ni o to yọri ero rẹ lori ọran na, o si gberasọ o dorikọ ọna ilu AIGBỌDỌJIYAN. Nigbati o kan ilu akọkan ti o nilati sun mọju nibẹ ki o to kọja si ibiti o nlọ, ni o ba ya sun nibẹ.

Nigbati o tọrọ aye lati sun ti nwọn si fun un, bi o ti fi ẹhin lelẹ lati ma a sinmi ni bale ile na ba sọ fun un pe, "bi enia ba jẹun tan, ko gbọdọ la ẹnu si atẹgun o." Ajapa si jẹ ẹ ni ho o, on ni on gba lati fi ara mọ ofin na.

Lẹhin ti Ajapa ti gba lati pa ofin yi mọ ni baale-ile na ba paṣẹ pe ki nwọn lọ ata-wẹwẹ panu kan, ki nwọn fi sa odidi akukọ adiẹ kan, ki nwọn ro ọka si i, ki nwọn si gbe e fun Ajapa ki o fi ṣe onjẹ alẹjẹsun.

Ajapa jẹ ọlọgbọn ati oloye pupọ, o si mọ ero baale-ile na. Bi nwọn ti gbe onjẹ yi kalẹ fun ajapa, ti nwọn si bu omi ti i, A japa yọ ekiri-ẹran meji ninu awo, o ṣin in nu dada ninu omi-iwẹwọ, o si fi jẹ onjẹ rẹ ni ajẹyo. O da omi ọbẹ na sinu awo-iwẹwọ, o da a sita, nwọn si palẹmọ onjẹ yoku lọ.

AJAPA ṢẸGUN

Ṣugbọn, "o ba mi, ko dun mi, ko jọ ti ẹniti kinikan nko ba rara." Ko pẹ pupọ ti Ajapa ti jẹun tan, ti nwọn si ti palẹmọ lọ ni gbogbo ẹnu bẹrẹsi ta a, ti agbari rẹ si ngbona foo, bẹni ko gbọdọ yata, ko si gbọdọ lanu si atẹgun.

Nigbati ko mọ ohun ti o le ṣe, ni o ba wo ra a-ra ara a kakiri, o si yara gba ọmọ ọsu mẹfa kan lọwọ iya rẹ nibti nwọn gbe nfun un lọmu ni ọdẹdẹ ibiti Ajapa wọ si, o si bẹrẹsi kọrin nfun ọmọ na bayi pe :-

"Ṣuba, ṣuba ṣu-bamba"
"Ṣuba, ṣuba ṣu-bamba"

Bayi ni Ajapa bẹrẹsi kọrin, ti o si ngbe ọmọ na jo kakiri ọdẹdẹ, ọmọ na si bẹrẹsi rẹrin lakọlakọ, o nfosoke ni ọwọ Ajapa, kẹrẹ-kẹrẹ bẹ ẹ, ẹnu Ajapa tutu, ko ta a mọ, ẹnikẹni ko si fura si i pe ọgbọn ni o nfi eyi da lati jẹki atẹgun le wọ ẹnu rẹ ki o si tutu fun ata-tita.

Ọna yi ni Ajapa gba ti o fi ṣẹgun idanwo rẹ kini ninu irin-ajo rẹ lọ si ilu Aigbọdọjiyan.

OFIN KEJI

Ni fẹẹrẹ ọjọ keji ni ajapa ba yara fo si ọna ilu Aigbọdọjiyan ti o nlọ. Ili o ti wọ ilu na ni o ba tọrọ aye lati wọ si ni ọdọ baale-ile kan, nwọn si gba silẹ. Ṣugbọn bi o ti nwọ ile na ni bale-ile na ba bere wipe, orukọ wo ni Ajapa njẹ. Ajapa si dahun pe MO-JI-MO-ṢU ni orukọ on njẹ. Nwọn si sọ pe ko buru, ṣugbọn ofin ti awọn fẹ sọ fun un pe ki o pamọ ni wipe ẹnikẹni ko gbọdọ ṣu tabi ki o yagbẹ, ko si gbọdọ tọ rara ni ilu yi, Ajapa ni ha ! On ko mọ wipe a ki iṣu, a ki i yagbẹ nilẹyi o, ṣugbọn on yio gbiyanju lati pa ofin na mọ, on ko ni ṣu, on ko si yagbẹ rara, gbogbo wọn si jẹun alẹ, olukaluku si lo si ibuṣun rẹ.

AJAPA RU OFIN

Nigbati o di oru ọganjọ ni igbẹ ba bẹrẹsi gbọn Ajapa, nigbati Ajapa ko si ri ibikan yagbẹ na si, ni o ba lọ sinu iyara ti baale-ile na gbe sun si, o si ṣu imi rapata kan si itosi isalẹ ibiti o gbe sun si, o ka aṣọ rẹ mọra, o si yọ kẹlẹkẹlẹ pada si aye ibuṣun rẹ.

Nigbati ilẹ mọ, ti baale-ile na ji, o dide o fi aṣọ rẹ pakaja, o fẹ lọ fi omi bo oju rẹ ni ile iwẹ ki o si run pako. Bi o ti gbe ẹsẹ kan siwaju lati ma a lọ, paṣa ! ni o ti ẹsẹ bọ imi ti Ajapa ṣu si itosi ọdọ rẹ loru.

Bale na si kigbe lojiji pe, "paṣa! Tani ṣu o, tani ṣu o?" Lẹsẹkẹsẹ na ni gbogbo awọn enia inu ile na ba taji loju orun ti gbogbo wọn si pesẹ si ọdọ rẹ kiakia nigbati nwọn gbọ wipe ẹnikan ṣu.

AJAPA KIGBE

Ṣugbọn Ajapa ko dide nilẹ, ko si fọhun si ọrọ na rara. Nigbana ni Baale na wa rin wa si itosi ọdọ Ajapa, o ni "Mo-ji-mo-ṣu," bi o kanran ki Ajapa dahun pe ho-o, nṣe ni o logun lojiji para pe :

"Ko o, ko o bẹrẹ ki o fi ọwọ ara rẹ ko o, bi o ba ṣu ki o ko o. Tabi alejo ni o

(Wo oju ewe kọkanla)




## Akiyesi fun awọn aṣoju wa ni Ghana

Gẹgẹbi a ti sọ fun nyin ni aipẹ yi pe, eto ti a nṣe nipa ki Iwe Irohin Yoruba tete ma a tẹ nyin lọwọ, a ṣi wa ni ori adehun na pẹlu awọn oniwe Irohin Graphic ti o wa ni Ghana, bi a ba pari adehun eto na, ẹ o ma a gbọ, ṣugbọn ko ni i pẹ mọ ki ẹ fi ọkan balẹ o. Ẹ ku iṣẹ o.

Olotu.

# Ọladunjoye Ajasa gbe ọmọ Oloye Coker ni iyawo



Ẹ̀ṣẹ awọn gbajumọ l'Eko ati ni Abẹokuta lo pe si Ṣọọṣi "St Paul's Anglican," Shomolu nibi isin alarinrin ti igbeyawo Ọgbẹni Ọladunjoye Ajasa ati Omidan Alice Ọmọlara Coker, laipẹ yi. Eni-owọ E. Ọla Oyebajo loṣe eto isin ọjọ na. Aworan oke yi ni ti ọkọ ati aya nigbati nwọn jade ni Ṣọọṣi. Baba iyawo na, Oloye E O. Coker l'Eko ni o wa lọwọ ọtun.

ỌTTA

OJỌ nla ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejilelogun osu kinni ọdun yi jẹ fun gbogbo awọn ara ilu Ọtta ati agbegbe rẹ. Ni ọjọ na ni awọn Musulumi Ọtta ati agbegbe ilu na pejọ bamu sibi eto kikan panu Mọṣalaṣi Jimọ Ọtta. Ogunlọgọ enia lo pesẹ sibi aṣeyẹ yi. Lati owurọ ni awọn enia ja-nkan ja-nkan si ti nwọ ilu Ọtta fun ti ipade ọjọ na.

Eto ọjọ na bẹrẹ pẹlu adura ti Alhadji Najimu ṣe. Lẹhin ni Alhadji Najimu tẹnu bọ ọrọ iwuri nipa wasi. Bi o si ti pari ọrọ wasi rẹ tan ni o ba fi oolu (hanma) le Alaṣẹ Ilu, Alhadji Seriki Bashọrun, lọwọ. Alhadji Bashọrun

## Ọba Onitsha w'aja

LATI Onitsha ni irohin ti kan wa pe Ọba Alaiyeluwa James Okosi Koji, Obi Onitsha w'aja ni Afin rẹ ni ọjọ Aje ti i ṣe ọjọ karun oṣu yi.

Gẹgẹbi aṣa iṣẹdalẹ ilu Onitsha, bi nwọn ti nsin oku ọba tan ni awọn afọbajẹ yio ṣe ikede lọjọ na gan an ẹniti yio bọ si ori oye.

## *Were ja o pa enia mẹfa*

TECHIMAN-Ghana

LẸNULỌLỌYI ni ọkunrin aṣiwere kan ja ni abule Krobo lẹba Techimna ni Ipinlẹ Brong Ahafo ni Ghana, o si pa awọn enia mẹfa patapata.

* * *


**Nihin ni IRORA rẹ wa**

*Iwe aworan yi ni o fi ibiti aisan gbe wa lara han nigbati awọn eree inu rẹ ko ba ṣiṣe deede*

**DeWitt's**

**Kidney & Bladder Pills**

**nse iṣẹ atunṣe eree inu taara ni lati ti oro inu ti o ngmu irora wa jade**

Lẹhin wakati diẹ ti o ba ti lo "De Witt's Pills" tan itọ rẹ yio mu awọ miran wa. Eyi ni ẹri pe oogun ti o yanilẹnu yi ti bẹrẹ si ṣiṣẹ niyẹn, o nda

LAKUREGBE, ARA-RIRO, ẸHIN-DIDUN ATI GBOGBO IYỌNU APO-ITỌ DURO



**DeWitt's**

**Kidney & Bladder Pills**

*O ju ogota ọdun lọ ti gbogbo enia ti o ti ni aisan ri yika gbogbo agbaiye ti ngyin wọn.*




Awọn enia po pupọ nibi aṣeyẹ ikomọ ti Ọgbẹni R. A. Shabi ati iyawo rẹ Iyaafin Sikirat Shabi ṣe ni ile wọn 6, Simpson Street, Ebute Mẹtta laipẹyi. Eto isọmọ-lorukọ na bẹrẹ ni owurọ, nwọn si sọ ọmọ na

# Awọn Musulumi Ọtta ṣi Mọṣalaṣi Jimọh titun

ṣe adura pupọ, Alhadji Awalye-waṣere na tun ṣe adura pẹlu. lẹhinna ni Alhadji Seriki wa fi oolu (hanma) na le Ogbẹni Fẹhintọla (kafinta) lọwọ lati kan ile na.

**IRO IBỌN**

Bi oolu (hanma) na ti dun bẹni iro ibọn paapa dun lẹmẹta, ariwo ba ta gee, awọn enia si bẹrẹsi yọ, nwọn nyọmbo Anabi. Lẹhinna ni nwọn wa bẹrẹsi fi owo tọrẹ adura fun anfani ati ifaiya balẹ ilu ati ọpọlọpọ ibukun fun awọn alaṣẹ ati awọn ara ilu pẹlu. Alhaji Arowoshafẹ ti o ṣe akọwe Alhaji Najimu ni o



ALHADJI NAJIMU

ṣe eto kiko owo na jọ, owo ti nwọn si ri gba lọjọ na jẹ £403. 15s.).

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn enia pataki-pataki bi awọn Alhadji, Lemọmu, awọn Ijoye, ati awọn obinrin ati awọn ẹgbẹ orisirisi ni Ọtta ati agbegbe ilu ti nwọn wa sibi aṣeyẹ yi ni awọn Ọlọla Alhadji Z. A. Ọpalẹyẹ, Alhadji Abudu Salami Adewunmi ti Ilaro, Alhadji Musa Lawal, Alhadji Sule Balogun ti Aiyetoro, Alfa Bello, Lemọmu Amadiyya, Alhadji L. A. Daodu Oni-tafsiri, Alhadji Ibatu, Alaga awọn Hujaj, ati awọn Igbimọ Eto kikọ Mọṣalaṣi ati ti ki kan Mọsalaṣi na.

Irohin ko to afojuba ni eyẹ ikirun akọkọ ninu Mọṣalaṣi nla yi ni ọjọ Eti ti i ṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni odo Ijana. Ni fẹrẹ ki ilẹmọ ni nwọn ti ta aṣia yi Mọṣalaṣi Jimọh na pọ. Alhadji Seriki ni o si ko gbogbo awọn janma lọ kirun ninu Mọṣalaṣi na, pẹlu Suberu Mosuro, Balogun Ọtta, Alhadji L. A. Salakọ, Balogun Imale. Alhadji Sule Noibi ni o ke "hutuba", Alhadji L. A. Daodu ni o si ṣe adura.

Alhadji Najimu ni o ṣe wasi ni ọjọ na. Ninu ọrọ iwuri rẹ, Alhadji Najimu sọ pe ko si ohun ti o dara to ifọwọsowọpọ lati ṣe iṣẹ Ọlọrun. O si tun tẹnu mọ ọrọ ifẹ. O ni ifẹ dara pupọ larin gbogbo enia, papapa larin gpbogbo Musulumi, nitori ibiti ifẹ ba gbe wa gbogbo nkan yio ma a lọ deede nibẹ. O si tun sọ nipa Mọṣalaṣi Jimọ. O ni

Lẹhin na ni Alhaji Seriki Baṣọrun ṣe adura le Alhaji Najimu Deen lori ni aṣe gbogbo awọn Janmọh Ọtta. Mọṣalaṣi na jẹ eyiti o tobi, pẹtẹsi ni, o si dara pupọ. Lẹhin isin ọjọ na ni Bẹmbẹ ati Aligota bẹrẹ si dun ti gbogbo enia si bẹrẹ si yọ. Awọn ọmọ ile Ekọ Asarudeen pọ pupọ ni ọjọ na awọn enia si to ẹgbẹrun mẹta lọkunrin ati lobinrin ti wọn wa ṣe isin ninu Mọṣalaṣi tuntun na.



MỌMỌ BADA



LEMỌMU FẸHINTỌLA



ALHADJI ỌLỌRUN-KẸMI



LEMỌMU RAJI



ALHADJI MỌMỌDU ARẸ



ALHADJI A. AROWOṢAFẸ

* * *

Mọṣalaṣi Jimọ jẹ nkan pataki ti ilu nla ko gbọdọ ma ni, o ni ṣe pataki-julọ nibiti Musulumi ba gbe pọ si. O ni irun Jimọ si tun jẹ irun akojọpọ ki fun gbogbo, eniti o ba nwa iyọnu ati ibukun Ọlọrun. Ni ipari ọrọ rẹ, Alhadji Najimu ka iwe owo ti awọn ti ri gba, gbogbo owo na si jẹ (£9,860).

Lẹhin ti Alhadji Najimu ti pari ọrọ rẹ ni gbogbo enia ba dupẹ lọwọ rẹ fun eto owo na ti o ṣe daradara. Lẹhinna ni nwọn da awọn marun lọla ninu awọn ti nwọn ba Alhadji Najimu ṣiṣẹ pọ. Ibi nwọn si ti nwe lawani oye fun wọn ni gbogbo enia nyọ, ti nwọn si nyin Ọlọrun logo. Awọn mararun ti nwọn fi lawani oye da lọla na ni aworan wọn wa loju ewe yi, awọn si ni:—Mọmọh Bada; Lemọmu Fẹhintọla; Alhadji Ọlọrun-O-Kẹmi ;Lemọmu Raji; Alhadji Mọmọdu, Arẹ; aworan alhadji Najimu ati ti Alhadji Arowo-shafẹ, Akọwe rẹ, wa loju we yi bakanna.



...ni Kuburat Ọmọtunde. Aworan oke yi ni ti igbati awọn nṣe inawo ikomojade na, ọmọ na ni o si wa lọwọ obirin to duru si arin aworan na.


WESTERN NIGERIA DEVELOPMENT CORPORATION

**VACANCY FOR ROAD OVERSEERS**

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Road Overseers in the Corporation.

**Qualifications:** Candidates should have had at least five years experience in the capacity of Road Overseer or Assistant Road Overseer in a Government Department preferably Ministry of Works and Transport or in a local Government organisation.

**Duties:** Successful candidates will be required to instruct, supervise and control labour and will also be required to apply the standard methods of road maintenance and construction on Corporation's Projects.

**Scale of Salary:** £407 x 21 — £491

**Method of Application:** Applications stating qualifications, age and experience with the names of three referees should be forwarded to the Secretary, Western Nigeria Development Corporation, Private Mail Bag No. 5085, Secretariat, Ibadan; to reach him not later than 28th February, 1961.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

Ibadan
30th Jan 1961.

# Ilu Aigbọdọjiyan

(Lati oju ewe kẹfa)

nko imi ọmọ onilu nileyi, ko o bẹrẹ ko o. Iya mi ko sọ mi ni mo-ji-mo-ṣu, Ajapa ni iya sọ mi."

Bayi ni ọrọ imi yi ba di ariyanjiyan larin Baale na ati Ajapa, ti nwọn si nti i si ara wọn pe, "iwọ lo ṣu, emi kọ ni mo ṣu, iwọ ni o ṣu imi na." Ṣugbọn nigbati nwọn ti mọ tẹlẹ wipe ẹnikẹni ninu awọn ara ilu na ki i ṣu, ki i yagbẹ tẹlẹri, Ajapa ni nwọn da ẹbi pe on ni o ṣu imi na, nwọn si sọ pe ki Abọrẹ oriṣa ilu na lọ pa a bọ Oriṣa.

### IDAJI ỌNA

Nigbati nwọn fa Ajapa le Abọrẹ na lọwọ tan lati lọ pa a bọ oriṣa, Abọrẹ na sọ fun Ajapa pe ki o rin niṣo nibiti on gbe nlọ pa a bọ oriṣa, ṣugbọn Ajapa sọ fun un pe on ko le rin, afi bi o ba le gbe on ru lọ sibẹ. Abọrẹ na si gbe Ajapa ru, o fa ada ti yio fi bẹ ẹ lori dani ni ọwọ ọtun, o si nlọ.

•Nigbati nwọn de idaji ọna, nwọn kan odo nla kan ti o wa ni idaji ọna si igbo oriṣa na, bi Abọrẹ na si ti fi ẹsẹ bọ omi na lati wọ ọ goke, ni Ajapa ba lọgun foo lojiji pe. "Iboo sioo! ẹja bu mi lẹsẹ jẹ o!!

Nigbati Abọrẹ gbọ igbe abosi ti Ajapa ke yi ati irọ ti o tun pa pe "ẹja bu on lẹsẹ jẹ," inu bi abọrẹ na pupọ, ko si ronu jinlẹ ki o to ja Ajapa ni koro lojiji bayi pe: "Ha! Ajapa irọ ni o kuku roju pa to bayi? o ma le dibọn pupọ o emi ti mo gbe ọ ru ti ẹsẹ mi mejeji si tun wa ninu omi, ẹja koi ti i bu mi lẹsẹ jẹ. Bawo ni ẹja ti ṣe rin ki o to de ibi ẹsẹ rẹ? Iwọ opurọ buruku yi!"

### AJAPA PA ABỌRẸ

Lẹsẹkẹsẹ ti Ajapa ti gbọ bayi, ni o ba fo bọ silẹ lati ori Abọrẹ na, o si na ika ẹsun si i loju pe, "o pari wayi, Abọrẹ ki jiyan o kọkọ gba ada-oriṣa lọwọ Abọrẹ na, o si wọ ọ goke odo lọ si idi oriṣa na, o bẹ ẹ lori sibẹ, o fi bọ oriṣa wọn na, o si pada lọ si ile rẹ. Bayi ni ofin Aigbọdọjiyan ti ṣe parẹ ni ilu ẸRIJIYAN na lati igbana lọ.

Ẹkọ ti a ri kọ ninu itan yi ni pe, ofin ti o ba ṣoro lati pamọ fun ẹnikẹni, ko yẹ ki a ṣe ofin na. Ohunkohun ti a ba si ṣe ni ofin, ẹnikẹni gbọdọ fi ọkan ran ofin na lati pa a mọ nigbagbogbo. O si jẹ iwa ọgbọn pupọ lati ma a ronu jinlẹ ki a to fesi si ọrọ tabi ibere ọta ẹni, ki a ma ba a lugbadi rẹ OHUNGBOGBO NFẸ IRONU-JINLẸ.

# Balogun Eko jalaisi

ALHAJI Oloye Amodu Ayinla Alli-Balogun Eko jalaisi ni alẹ ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogbọn oṣu ti o kọja yi, ni ile rẹ, 29 Princess Street l'Eko, nigbati o di ẹni ọdun marundinlogbọn ti o si ti ṣe aisan fun ọjọ diẹ.

Ẹsẹ awọn Alhaji, Lemọmu, Alfa ati gbajumọ ni o pe ṣoṣọ si Itẹ oku Oke Suna nibiti nwọn gbe oku rẹ si, ni ọjọ keji ti o ti ku Lemọmu-Agba Liadi Ibrahim ni o kirun si i lara. Awọn ti o wa si ibi isinku na le ni ẹgbaa (2,000) enia.

Lemọmu-Agba sọ ọrọ apọnle nipa ologbe na bi o ti ṣe jẹ olufọkansin, ọlọyaya, alawada, enia tutu, onilakaye ati oninure, si nigba aiye rẹ. Awọn ọmọ oku na si na owo pupọ ni ibi aṣeyẹ isinku ologbe na. Ọmọ mẹwa ni o fi si aiye lọ.

## Ọmọle ṣe ase ajọyọ ọdun

AKIM MANSO Ghana

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Adedoyin Ọmọle se ase ajọyọ ọdun fun awọn ọrẹ rẹ ati awọn ojulumọ ti o wa ni Akim-Mano Ghana.

O si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn ti o pe wa si ibi ase na lọrun, awọn onilu ṣẹkẹrẹ ati aro lati Naijiria si fi gọngọ ilu wọn dabira l'ọjọ na.

Aṣ'eyi ṣ'amọdun o.

# A W Ẹ

(Lati oju ewe karun)

O ṣeni lanu lati ri pe ọpọlọpọ ti nwọn ni awọn ngba Awe, dabi ẹniti o ntan ara rẹ jẹ. Gẹgẹbi Alhaji Mohamed ti Iwo ti wi sinu iwe "Irohin Yoruba" ti ọsẹ ti o kọja, ogunlọgọ lo ti ro pe bi awọn ba ti gba Awẹ fun oṣu kan yi, gbogbo ẹsẹ ti awọn ti ṣẹ fun oṣu mọkanla yio parẹ, nitori, ni ẹnu wọn, "oṣu pa-ẹṣẹ-rẹ pa-ẹṣẹ-rẹ" ni oṣu "Ramulan." Ẹyi ki i ṣe bẹ.

Gbogbo awọn eni lailai ti ngba Awẹ ki i gba nitori a ti yọ ẹsẹ oṣu mọkanla. Awẹ gbigba jẹ ọranyan gẹgẹbi awọn Musulumi ti ni igbagbọ si, ṣugbọn o yẹ ki awọn ti nwọn jẹ olori ijọ Musulumi o ma a tẹ mọ awọn janma wọn leti firifiri pe nkan ti mbẹ ninu Awẹ gbigba ju ki a ma jẹun tabi ki a ma mumi lọ.

Bi enia ba le se ara rẹ ro ninu iṣẹ buburu, ninu iṣọkuṣọ, irin-kurin, ijẹkujẹ, iwo-kuwo, fun ọgbọn ọjọ, eeṣe ti oluwarẹ ko nile ṣiwọ kuro ninu gbogbo iwa ibi wọnyi fun gbogbo oṣu mọkanla yoku?

Awẹ je nkan pataki fun gbogbo Musulumi, gbogbo fere ti o si wa ninu oṣu na ni ki Oluwa ko se fun wa,

Ki Oluwa jọwọ ninu anu Rẹ, ki o mu idẹra wa fun gbogbo wa, ki Ominira ti a gba yi o jẹ ti anfani, ki ilu wa roju, ki ojo anfani, ojo idẹra, ojo alafia o ma a rọ si ilẹ wa na, ki a ma rogun, ki a ma ri iyan, ki a ma ri ọda owo.

Mo ki gbogbo Musulumi nwọn ku ipamọ awẹ, Oluwa jẹ ki ẹmi wọn o gba a ja!


Nikehin wayi

abẹ infarungbọn to mu julọ




Obe Alafẹfẹ NACET Ọlọni

Trade enquiries to: R. E. HARDING & CO. LTD · LAGOS · ABA · KANO

